## Ǹjẹ́ àwọn ìdíjú kankan wà?

Ó wọ́pọ̀ láti ní ojú wúwú, pípọ́n tàbí rírọ̀ níbití o ti gba abẹ́rẹ́. Nígbà míràn ojú wúwú kékeré tí kò nira kan má ń wáyé, sùgbọ́n èyí má ńsábà pòórá lẹ́yìn ọ̀sẹ̀ díẹ̀. Àwọn ìdíjú tó le kò wọ́pọ̀ sùgbọ́n ó pẹ̀lú ibà, orí fífọ́, ojú sísú tàbí níní ìmọ̀lára dídákú àti àwọn ìsun ara wúwú.

Bí ara rẹ kò bá yá lẹ́yìn gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára, lo paracetamol. Ka àwọn ìtọ́sọ́nà tó wà lára ìgò tàbí páálí dáradára kí o sì lo òògùn tó yẹ fún ọjọ-orí rẹ. Bí ó bá nílò, lo òògùn kejì ní wákàtí mẹrin sí mẹ́fà lẹ́yìn náà.

Bí ara rẹ bá sì gbọ́ná síbẹ̀ lẹ́yìn abẹ́rẹ́ kejì, bá GP rẹ sọ̀rọ̀ tàbi kí o pe òpó ìrànlọ́wọ́ ọ̀fẹ́ NHS 111.

Bí o bá ní ìrírí èyíkèyí àwọn ìdíjú sí abẹ́rẹ́ àjẹsára náà tí o furasi, O le jábọ̀ èyí lórí ojú-ewé káàdì Yellow (Yellow Card) tàbí nípa pípe 0800 731 6789 (agogo 9 òwúrọ̀ si 5 ìrọ̀lẹ́ Ọjọ́ Ajé sí Ẹtì) tàbí nípa gbígba ápùù Yellow Card sílẹ̀ sórí ẹ̀rọ. **www.mhra.gov.uk/yellowcard**

## Ìsisìnyí ni àkókò dídára làti ṣe àyẹ̀wò wípé o ti gba àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ pé

| Àwọn àjẹsára fún àwọn ọ̀dọ́ | Abẹ́rẹ́ àjẹsára NHS |
|---|---|

Fún ìwífún síi nípa àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára àgùnbánirọ̀ ṣe àbẹ̀wò sí **www.nhs.uk/vaccinations** tàbí kí o ka **https://qrco.de/YoungPeopleImms**



**Kò tíì pẹ́ jù láti dójúìwọn pẹ̀lú gbígbà àwọn abẹ́rẹ́ tí o ti le pàdánù.**

Ìwé pélébé yìí ni a ti pèsè láti ọwọ́ Àjọ Àbò Ìlera UK (UK Health Security Agency).

© Crown copyright 2023. 1P 100K JULY 2023 (APS). Product code: YP3BG1YO Yoruba. UK Health Security Agency gateway number: 2023193.

O le bèèrè fún tàbí gba ìwé pélébé náà sórí ẹ̀rọ rẹ láti: www.healthpublications.gov.uk, nipa pipe: 0300 123 1002
(Àwọn òpó sí sílẹ̀ ni Agogo 8 òwúrọ̀ sí 6 ìrọ̀lẹ́, Ọjọ́ ajé sí Ẹtì).

Àwọn ẹ̀dà ìwé pélébé yìí ní èdè Gẹ̀ẹ́sì wà ní àrọ́wọ́tó láti bèèrè fún.

Àwọn ẹ̀dà tí a túmọ̀ ìwé pélébé yìí sí tún wà ní àrọ́wọ́tó láti bèèrè fún.

UK Health Security Agency

# Td/IPV àlékún àgùnbánirọ̀ 3 nínú 1



Ní ọdún 14 tàbí l'ásìkò Ọdún 9 ilé-ẹ̀kọ́ ni o ti yege fún abẹ́rẹ́ àjẹsára àlékún àgùnbánirọ̀ 3 nínú 1 tí ò ńdènà àárùn wayínlù, diphtheria àti rọpá-rọsẹ̀. **Abẹ́rẹ́ àjẹsára Td/IPV ṣe àlékún àjẹsára ara rẹ sí àwọn àárùn àrànmọ́ tí o ti le dínkù bí o ti dàgbà.**

## Kínni abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí npamímọ́ kúrò?

**W**

### Wayínlù

Wayínlù jẹ ààrùn to nira ti nkoba ètò-iṣẹ́ ara èyítí o le yọri si isan gbigbọn, nfa àwọn isoro eemi, o si le pani. O nwaye nígbàtí àwọn kòkòrò to wa ninu yepẹ ati ilẹdu wọnu ara nipasẹ àwọn apa tabi ijona sisi. Wayínlù kole ran lati ẹnikan si ẹnikan.

---

**D**

### Diphtheria

Diphtheria jẹ ààrùn lile to ma nsaba bẹ̀rẹ̀ pélú ọgbẹ ọna ọfún o si le tete fa àwọn isoro eemi. O le ṣe ipalara ọkan ati ètò-iṣẹ́ ara, ati ninu àwọn iṣẹlẹ lile, o le pani.

---

**IPV**

### Rọpá-rọsẹ̀

Àìsàn rọpá-rọsẹ̀ jẹ́ kòkòrò àìlefojúrí kan ńfà èyítí ó ńdojúkọ ètò-iṣẹ́ ara èyítí ó le fa isan ríro pátápatá. Bi o ba koba àwọn isan aya tabi ọpọlọ, àìsàn rọpá-rọsẹ̀ le pani.

---

Abẹ́rẹ́ àjẹsára agunbanirọ ni à ńpè ní Revaxis, o le ka Ìwé-pélébé Ìwífún Aláìsàn ní **www.medicines.org.uk/emc/product/5581/pil**

### Bi mo ba ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tako ààrùn wayínlù, diphtheria ati rọparọsẹ gẹgẹbi ọmọ kan, njẹ mo si tún ni wa ni ààbò lẹkunrẹrẹ?

Rara, o si tún nílò àlékún kan lati de ààbò ti o ti gba ri l'ade.

### Àlékún abẹ̀rẹ̀ méèló ni mo nílò lati ni?

O nílò apapọ abẹ́rẹ́ àjẹsára kòkòrò wayínlù, diphtheria ati rọparọsẹ marun lati ṣe igbesoke ati pa àjẹsára rẹ mọ.

O yẹ ki o ti gba:



**Àwọn abẹ́rẹ́ 3 akọkọ**
gẹgẹbi ikoko

---



**Abẹ́rẹ́ 4**
nígbàtí o wa laarin ọmọ ọdun 3 ati 5, eyi ni àlékún jẹleosinmi náà

---



**Abẹ́rẹ́ 5**
ti pe ni ọdun 9
(ọjọ-ori 13 si 14)

### Ǹjẹ́ mo nílò àwọn àlékún siwaju sii ni ọjọ iwaju?

O ṣeeṣe ki o ma nílò àwọn àlékún abẹ́rẹ́ àjẹsára wọnyi siwaju sii. Ẹwẹ, o le nílò àwọn afikun abẹ́rẹ́ àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára kọọkan bi o ba nsabẹwo si àwọn orilẹ-ede kọọkan tabi bi o ba ni ipalara kan, o le nílò abẹ́rẹ́ wayínlù miiran. Ṣe ayẹwo pélú nọ́ọ̀sì rẹ nibi iṣẹ abẹ GP rẹ.

### Bawo ni maa ṣe fún ọ ni àlékún Td/IPV?

O gba abẹ́rẹ́ kan ni oke apa rẹ. Kosi ẹniti o fẹran abẹ́rẹ́, sùgbọ́n o yara kiakia. Àwọn abẹ́rẹ́ ti alo keere o si yẹ ki o ni imọlara inira kekere. Bi ẹru ba nba ọ díẹ̀ nipa gbigba abẹ́rẹ́, sọ fu nọ́ọ̀sì tabi dokita sáájú ki o to gbaa.

### Njẹ àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára mìíràn tún wa ti o yẹ ki ngba nibayi?

Nígbàtí o ba ngba àlékún abẹ́rẹ́ Td/IPV rẹ o tún ma yẹ fún abẹ́rẹ́ àjẹsára MenACWY rẹ. O gbọ́dọ̀ ni eyi sáájú ki o to kuro ni ilé-ẹ̀kọ́. Ba nọ́ọ̀sì ilé-ẹ̀kọ́ rẹ sọrọ bi o ba ti kuna ti o si tún wa ni ilé-ẹ̀kọ́. Bi o ba ti kuro ni ilé-ẹ̀kọ́, o gbọ́dọ̀ kansi GP rẹ lati s'eto bi o ṣe ma dojuiwọn. O jẹ ohun ti o bojumu lati ṣe ayẹwo pélú GP rẹ wípé gbogbo àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ yooku pe pélú HPV ati MMR (ìta, ibà àti àpọ̀ ìtọ̀ wíwú tí o le gan ati ìta pipọn).

**Bi o ko ba tii gba abẹ́rẹ́ àjẹsára MMR, o gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ kan nibayi ati osu kan miíràn to baya lati dabobo ọ lọwọ Ìta, ibà àti àpọ̀ ìtọ̀ wíwú tí o le gan ati ìta pipọn.**

